| Gbogbo Àkókò |
| --- |
| **Ìṣẹ́jú Marundinlaadọta siàwọ Wákàtí kan** |

| Ọjọ́ Orí |
| --- |
| **méjọ sí mọ́kànlá** |



# Gbogbo Ènìyàn Ni Ó Lè Jẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa

## Àwọn Àbájáde Ẹ̀kọ́

- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò ní òye ohun tí ń sọni di Olùṣọ́-Ìlépa fún àwọn SDGs.
- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò mẹ́nubà àti ní òye àwọn ọgbọ́n ìṣe àti ìmọ̀ tí wọ́n ti ní láti lè dásí àwọn SDGs
- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò kọ́ láti fi èrò wọn múlẹ̀

## Kayan Aiki
## Àwọn Ohun Àmúlo

Ẹ̀kọ́ yìí ṣe é ṣe pẹ̀lú tàbí laisi ẹ̀rọ ayélujára

Pẹ̀lú ayélujára: kámẹ́rà tàbí kámẹ́rà ẹ̀rọ alágbèéká/ kọ̀mpútà/áípadì láti kò fọ́tò àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sí ojú ààpù (app) Goalkeeper Me.

Bí kò bá sí ayélujára: gègé ìkọ̀wé, àwọn ọ̀dà, ohun èlò fun àkójọpọ̀ iṣẹ́ àwòrán, dígí àti ìwé fún iṣẹ́ àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa (The Goalkeeper Portrait activity sheet).

## Ojú Ìwòye Tó Gbòòrò Si Lórí Sísé Àkọsílẹ̀ Ẹ̀kọ́

Ètò ẹ̀kọ́ yìí gbèrò láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbàgbọ́ pé olúkúlùkù ló ní agbára láti lè di Olùṣọ́-Ìlépa àti láti gbé ìgbésẹ̀ fún SDGs (Àwọn Ìlépa Àgbáyé). Nípa níní óye wípé oníkálukú ló yẹ kí ó darapọ̀ fún àṣeyọrí àwọn Ìlépa yìí, àwọn akẹ̀kọ̀ọ́ yóò ṣ'èdámọ̀ wọn a sì tún mọ rírì orísirísi ọgbọ́n ìṣe ẹnìkọ̀ọ̀kan wa àti ti ara wọn pẹ̀lú. Ètò ẹ̀kọ́ yìí tọ́kasí àwọn àmúyẹ gbòógì ọdún 2018 tí OECD Pisa Assessment Framework: Global Competence. Èyí tí a yànyànná rẹ̀ wípé, "agbára láti sàyẹ̀wo ọ̀rọ̀ abélé, àgbáyé àti ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà, láti ní òye àti ìmọrírì ojú ìwòye elòmíràn, láti kópa nínú ìbáṣepọ̀ tí kò farasin, t'ótọ́ àti tómúnádóko pẹ̀lú àwọn èèyàn-án onírúurú àṣà àti láti gbé ìgbése fún àlàfíà ati ìdàgbàsókè tó dúró ṣinṣin."

http://www.oecd.org/pisa/pisa-2018-global-competence.htm


In partnership with
Supported by
With thanks to
Endorsed by

**Àkíyèsí fun àwọn Olùdánilẹ́kọ̀ọ́**
Ninu ẹ̀kọ́ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò ronú jinlẹ̀ lórí ọgbọ́n ìṣe, ìwà àbùdá ati ìmọ̀ won nípa yíya aworan Olùṣọ́-Ìlépa kan. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ míràn lè má faramọ́ yíya fọ̀tò ara wọn. Nípa bẹ́ẹ̀, a lè ní kí wọn ya àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa ti ẹlẹgbẹ́ wọn tàbí ti gbajúmọ̀ Olùṣọ́-Ìlépa àwọn SDGs.

Pe Ẹ̀kọ́ yìí ní láti ṣe pẹ̀lú gbígbé fọ́tò/àwòrán di ori ẹ̀rọ ayélujára. Rìí dájú wípé ó wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ilé-ìwé rẹ àti ìlànà ìdáàbòbò àti kí ọ ka àwọn Òfin àti Ipò ti ó ní orí áápù Goalkeeper (Goalkeeper app): http://cdn.worldslargestlesson.globalgoals.org/2018/06/goalkeeper-privacy1-1.pdf

## Ìdúpẹ́

Pẹ̀lú ọpẹ́ pàtàkì sí **Chris Gadbury**, Twitter: @chrisgadbury www.magicstorybooks.com,
**Memory Banda:** https://memorybanda.blogspot.com/
**Ndubuisi Uchea & Hayel Wartemberg:** https://wordonthecurb.co.uk/
**Odeogbola Ayodele, Adeeko Olalekan** - Abeokuta Grammar School, Abeokuta ati Baptist Boys' high School Abeokuta (mejeeji ni Nigeria)

### Ìránnilétí Ìmọ̀ Àtẹ̀yìnwá

**Ìṣẹ́jú Màrún**

**Àkíyèsí:** Ẹ̀kọ́ yìí gbàgbọ́ pe àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ìmọ̀ nípa àwọn SDGs. Atọka ìtàkùn àgbáyé fún ìwo-àràa Ẹ̀kọ́ Àgbáyé T'ótóbi Jùlo (World's Largest Lesson) Apá Kínní tí ó ṣe àgbékalẹ̀ àwọn Ìlépa náà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wà ní http://worldslargestlesson.globalgoals.org/resources-for-teaching-the-sdgs-in-nigeria/

Bèèrè àwọn ìbéèrè wọnyí fún àtúnyẹ̀wò ìmọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lórìi àwọn SDGs. Èyí ṣe é ṣe bíi iṣé Àdárò, Ìdarapọ̀ Pẹ̀lú Ẹlòmíràn, Alábàápín, tàbí ti Gbogbo *Kíláàsí. Kíni àwọn ohun tí àwọn SDGs yìí fẹ́ jẹ́ kó di mímú ṣe? Kíni idí tí wọ́n fi ṣe pàtàkì? Àwọn Ìlépa méèló ni ó wà níbẹ̀?*

### Ìgbésẹ̀ Kejì: Ṣíṣe Ìdánimọ̀ Àwọn tó ń Ran Àwọn Ìlépa Tó Dúró Ṣinṣin Lọ́wọ́

**Ìṣẹ́jú méwàá**

Bèèrè ìbéèrè yìí lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́: *Ojúṣe tani iṣàṣeyọrí àwọn SDGs?*
Àwọn Àbá Tí Ọ lè Jẹyọ: Àwọn Ìjọba, Àwọn Àjọ Tí Kìí Ṣe Ti Ìjọba/Àwọn Àjọ Onínúure, Àjọ UN, àwọn okòwò, àwọn ọmọdé, àwọn àgbàlagbà – GBOGBO ÈNÌYÀN!
Bèèrè ìbéèrè tí ó tẹ̀le yìí: *Ṣé àwọn ọ̀dọ́mọdé ní ojúṣe láti rìí wípé àwon SDGs di mímú ṣe? Ṣe àwọn odomode lè mú iyàtò bá àwọn SDGs?*

Jíròrò lórí àwọn oríṣiríṣi ìdáhùn ati àbá kí ọ sí tún ṣàlàyé wípé láti ọjọ́ orí t'ókéré ní àwọn ọmọdé àti ọ̀dómọdé lè ti kó ipa tó yanrantí lórí àwọn Ìlépa. Wo apá Kejì ìwò-àrà Ẹ̀kọ́ T'ótóbi Jùlọ L'ágbàáyé (the World's Largest Lesson Part 2 animation) ní orí (http://worldslargestlesson.globalgoals.org/resources-for-teaching-the-sdgs-in-nigeria/) láti rí àpẹẹrẹ àwọn ọ̀dómọdé lásán tí wọ́n gbé ìgbésẹ fún àwọn Ìlépa. Òtún lè fi àwọn àpẹẹrẹ han àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti orí maapu ìbáṣepọ̀ ti Ẹ̀kọ́ T'ótóbi Jùlọ L'ágbàáyé (World's Largest Lesson interactive map) kí ọ sì wo àwọn ìgbésẹ tí àwọn ọ̀dọ́mọdé yòókù gbé fún àwọn SDGs.

Ṣàlàyé wípé a lè pe àwọn èèyàn wọnyí ni ***Àwọn Olùṣọ-Ilepa*** nítorí wípé wọn dúró fún àwọn SDGs wọ́n sì tún gbé ìgbésẹ fún un. Èèyàn lásán náà ni wọ́n tí wọ́n fẹ́ kí ilé-ìwé, ilé, agbègbè àti orílẹ̀-èdè wọn dárasi fún gbogbo ènìyàn láti gbé nííṣi yìí wọ́n sì tún ṣaláàbòo rẹ̀ fún ọjọ́ iwájú. Wọ́n ń fi àwọn Ìlépa náà ṣe ọ̀nà tí ó ń tọ́ka sí ìgbésẹ wọn sí ètò Ìdàgbàsókè Tó Dúró Ṣinṣin kan láti rìí wípé a ní ayé òdodo àti àìṣe-ojúṣàájú.

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè kà si lórí àwọn ọ̀dọ́ Olùṣọ́-Ìlépa míràn káàkiri àgbáyé ní Atọ́kasí kínní **Appendix 1-4**.


SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

## Ìgbésẹ̀ Kẹta: Ṣíṣe Àsopọ̀ Àwọn Ọgbọ́n Ìṣe Àwọn Èèyàn Fún Ìlépa

**Ìṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dógún**

**Àkíyèsí:** Ní iṣẹ́ ṣíṣe tí ó wà lábẹ́ yii, a kò ní ìdáhùn t'ótọ́ tàbí tí kòtọ́. A ṣe iṣẹ́ ṣíṣe náà láti lè dá ìjíròrò sílẹ̀ láàárín àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa bíbèrè àwọn ìbéèrè tí yóò pe àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níjà láti lè fi ẹsun àwọn àbá ati èrò wọn múlẹ̀.

Káà síta/ṣe àfihàn àkọsílẹ ọ̀rọ̀ láti ẹnu Olùṣọ́-ìlépa Memory Banda (wo **Appendix 3** láti mọ̀ si nípa iṣẹ́ àwàkọhà Memory lórí mímú Ìlépa kàrún (Goal 5) ṣẹ.

*"kò sí agbára tó ga jù lọ fún ènìyàn láti di Olùṣọ-Ìlépa. Gbogbo wa ni a lè di Olùṣọ́-Ìlépa nipa yíyan èyíkéyìí nínú àwọn SDGs yìí kí ọ sì bẹ̀rẹ̀ sí làkàkà fún ìtẹ̀síwájú."*

Jíròrò lórí àkọsílẹ̀ yìí nínú kílàsì - *ǹ jẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbàgbọ́?* Ṣàlàyé pé gbogbo wa ni a ní oríṣiríṣi ọgbọ́n ìṣe àti ìmọ̀ láti lè rìi wípé àwọn Ìlépa yìí di mímúṣe. Bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ báṣe lo àwọn ọgbọ́n ìṣe àti ìmọ̀ wọn yìí ni ó ṣe pàtàkìt. Bí Olùṣọ́-Ìlépa kan bá pinnu láti dìde láti gbé ìgbésẹ - bí ó tilẹ̀ rí àwọn ìfàsẹ́yìn ati ìjákulẹ̀, kí ó ní ìrètí, ṣe ọkàn akin, kí ó sì pinnu wípé Ìlépa náà yóò di mímú ṣẹ.

Fi ìwé-iṣẹ́ẹ 'Ṣíṣe Àsopọ̀ Láàárín Àwọn SDGs' han (**Appendix 5**). Iṣẹ́ ṣíṣe yìí wà láti ran àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́ láti mọ irúu ọgbọ́n ìṣe yi en nípò láti ṣe àmúṣẹ àwọn Ìlépa kọ̀ọ̀kan. Ṣàfihàn àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́ẹ̀dógún tí a dáládàá tí a kọ ni aláwọ̀ ewé ni Atọ́kasí Keta **Appendix 6** (o lè ṣàtúnṣe àwọn àkójọ yìí fún ilé-ìwé rẹ) Mú ọ̀rọ̀ kan láti bẹ̀rẹ̀ b.a. alátinúdá. Kọ èyí sí inú àwòrán onígun mẹ́rin àkọ́kọ́ tí ó wà láàárín ìwé iṣẹ́ ṣíṣe.

Bèèrè lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́- *Bawo ni ìṣe àtinúdá má ṣee kópa nínú àwọn Ìlépa yìí? Àwọn Ìlépa wo ni yóò nípa lé lórí jùlọ?* Gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti fi àwọn àbá ati ìdáhùn wọn múlẹ̀. Gba àwọn àbá díẹ̀ lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí o sì so àtinúdá mọ́ Ìlépa tí wọ́n yàn nípa fífa ilà láti ọ̀rọ̀ náà sí Ìlépa tí ó yẹ.

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ le parí iṣẹ́ ṣíṣe yókù nípa mímú àwọn ọgbọ́n ìṣe tí ó wà ní (**Appendix 6**) tí wọ́n ròpé á ṣe pàtàki jùlọ sí ìmúṣẹ àwọn Ìlépa. Kí wọ́n sì so àwọn ọgbọ́n ìṣe yii mó àwọn Ìlépa tí wọ́n rò pé yóò ṣe e lóore jùlọ.
Láàárín gbogbo iṣẹ́ ṣíṣe yìí, dá àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dúró láti bèrè irú ìṣe wo ni wọ́n rí gẹ́gẹ́ bí èyí tó ṣe pàtàkì jùlọ. Jẹ́kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣalábàápín àwọn àbá wọn lórí ìdí tí wọ́n fi yan ọgbọ́n ìṣe kan fún Ìlépa kan.

**Àkíyèsí:** Kòsí ìdáhùn t'ótọ́ tàbí tí kòtọ́. Ìdáhùn wọn dúró lóri bí wọ́n ba fẹ́. Àwọn ọgbọ́n ìṣe míràn lè jẹ mọ́ gbogbo àwọn Ìlépa.

**Ìpèníjà:** Bèèrè lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ *ìdí tí ó ṣe ṣe pàtàkì kí oríṣiríṣi àwọn ènìyàn pẹ̀lú oríṣiríṣi ọgbọ́n ìṣe, ẹ̀bùn, ìmọ̀ àti ìfẹ́ ran ìmúṣẹ àwon Ìlépa wọ̀nyí lọ́wọ́?* Nítorí wípé àwon ìṣòro tí àwọn ènìyàn ǹ kojú tóbi ó sì jẹ́ ojírúurú. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, kòsí ìdáhùn tàbí ọ̀nà àbáyọ kan sí wọn.

## Ìgbésẹ̀ Kẹrin: Mímọ Ipá Olúkúlùkù

**Ìṣẹ́jú méwàá**

Ìgbésẹ̀ tí ó kàn ni kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ ọgbọ́n ìṣe tójẹ́ ti wọn. Pe àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí wọ́n fi ìgbà díẹ̀ ronú jinlẹ̀ lóró àwọn ìdáhùn wọn sí àwọn ìbíèrè wònyí. Wọ́n le fẹ́ gbìmọ̀ pẹ̀lú alájọrò kan fún àfikún àwọn àbá.

1. *Kíni ohun tí ó ṣe pàtàkì nípa à rẹ tí ó jẹ́ kí o yàtọ̀?*
2. *Kíni ohun náà nípa à rẹ tí ó fi jẹ́kí o ní ipá/agbára láti di Olùṣọ́-Ìlépa?*
3. *Kíni àwọn ọgbọ́n ìṣe tàbí ìṣesí tí o ti ní tí o lè mú gbòòrò síi láti di Oùṣọ́-Ìlépa?*
4. *Irú èèyàn wo lo fẹ́ jẹ́ bí o bá dàgbà?*

Rọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nìyànjú láti ronú jinlẹ̀ kí wọ́n sì mú iyekíye ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá fẹ́. Ó ṣe pàtàkì láti tẹnu mọ́ o fun àwọn wípé kí wọ́n ṣe yan àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ṣe àpèjúwe ìrínisí ṣùgbọ̀n àwọn ọ̀rọ̀ tí ó júwe ìṣesí, ọgbọ́n ìṣe àti ìmọ̀. Fún àbá, o lè yẹ àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ sí **Appendix 6.**


SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

## Ìgbésẹ̀ Karùn-ún: Yíya Àwòràn Olùṣọ́-Ìlépa

**Ìṣẹ́jú méwàá**

Fí àápú Olùṣọ́-Ìlépa (Goalkeeper Me app) han. Ṣàlàyé pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní láti mú ọ̀rọ̀ mẹ́ta tí wọ́n gbàgbọ́ pé yóò ràn wọ́n lọ́wọ́ bí wọ́n ṣe gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs. Lo àǹfàní yìí láti ṣàlàyé pé gbogbo rẹ̀ dá lórí gbígbà wípé gbogbo wa yàtọ̀ sírawa ati wípé ìfẹ́ wọn ati ìfojúsùn wọn ni a ní lò fún ìmúṣẹ àwọn SDGs. Ọ lè fi àpẹẹrẹ àwọn àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa hàn wọn ní: http://perfectdaylondon.com/projects/goalkeepers/

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbe fọ́tò wọn sí orí ìtàkùn áàpù Olùṣọ́-Ìlépa  (the Goalkeeper app website). Wọ́n lè ṣe àwòrán wọn bó ṣe wùn wọ́n pẹ̀lú àwọ̀ àti àwọn ọ̀rọ̀. (Wo **Appendix 7** fun ìtọ́nisọ́nà lẹ́ẹ̀kún rẹ́rẹ́).

Jẹ́kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ronú jinlẹ̀ lórí àwọn ọ̀nà tí wọ́n lè gbà lo àwòrán Olùṣọ́-ìlépa wọn láti ran àwọn èèyàn lọ́wọ́ sí láti mọ̀ nipa àwọn SDGs. Ṣe àfihàn àwọn àpẹẹrẹ bí a ṣe ṣàgbéjáde àwọn Olùṣọ́-ìlépa àtẹ̀yìnwá ni New York ní ọdún 2017. *Ǹjẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ṣe ìpolongo Olùṣọ-Ìlépa ti won?*

**Ìdàkejì:** Bí kò bá sí kámẹ́rà, pèsè dígí kí o sì pe àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti yà/kùn tàbí ṣàkójọpọ̀ àwọn àwòrán ara wọn.. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè lo àwòrán yìí ati àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́ta tí wọ́n Yàn láti ṣe àwòrán Olùṣọ́-ìlépa.  (Wo àwòṣe àwòrán Olùṣọ́-ìlépa ni **Appendix 8**). A lè ṣàfihàn àwọn àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa yìí nínú kílàsì tabi ilé-ìwé. . Jẹ́kí àwọn ọmọ ilé-ìwé sọ àwọn ìbòmíràn ti a lè ti ṣàfihàn àwọn àwòrán yìí. *Ibo ni wọ́n lè tí ṣàfihàn àwọn àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa wọn ki àwọn ènìyàn lè bá mọ̀ nipa awọn SDGs?*

## Ìgbésẹ̀ Kẹfa: O Ti Ṣetán Báyìí – Gbé Ìgbésẹ̀

**Ìṣẹ́jú méwàá**

Níwọ̀nba ìgbà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ṣe ìdámọ̀ àwọn ọgbọ́n ìṣe àti ìmọ̀ tí wọ́n ní láti di Olùṣọ́-ìlépa, wọ́n ti ṣetán láti gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs! Béèrè àwọn ìbéèrè wọ̀nyí lè àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fún ìjíròrò gẹ́gẹ́ bíi ìsọ̀rí kan:

- Àwọn ìgbésẹ̀ wo lo lè bẹ̀rẹ̀ sí gbé lónìí?
- Kílẹ fẹ́ṣe fún àwọn Ìlépa gẹ́gẹ́ bíi ìsọ̀rí?
- Kíni àwọn ìbéèrè tí a ní fún àwọn Ìlépa?

Wo apá keta Ẹ̀kọ́ T'ótóbi Jùlọ L'àgbàáyé ni http://worldslargestlesson.globalgoals.org/resources-for-teaching-the-sdgs-in-nigeria/ fún ìmísí lórí bí o ó bẹ̀rẹ̀ lónìí!

Jọ̀wọ́ ṣalábàápín àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa rẹ pẹ̀lú wa! Darapọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹgbẹgbẹ̀rún ọ̀dómọdé Olùṣọ́-Ìlépa míràn nípa fifi ẹ̀kọ́ rẹ̀ẹ sí orí máàpù ìbáṣepọ̀ (our interactive map.) o tún lè báwa sọ̀rọ̀ lórí twitter ni @WorldsLessonNG, Facebook @WorldsLessonNG, Instagram @WorldsLessonNG or tàbí fìwé ránṣẹ́ sí worldslessonnigeria@outlook.com

**Àfikún Iṣẹ́ Ṣíṣe:**

- Fi Student Action tab han àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lórí ìtàkùn àgbáyé Ẹ̀kọ́ T'ótóbi Júlo L'ágbàáyé (the World's Largest Lesson website) http:// worldslargestlesson.globalgoals.org/ fún ìmísí lórí bí a ṣe lè gbé ìgbésẹ̀ fún SDGs.
- Dá Iṣẹ́ Ìṣakitiyan Fún Agbègbè sílẹ̀ láti mú àyípadà báa: http://worldslargestlesson.globalgoals.org/student-led-change-projects/
- Wo fídíò kékeré yìí https:// vimeo.com/268764152,) lóri àwọn gbajúgbajù àtijọ́. Bi àwọn akẹkọ̀ọ́ ní àwọn ìbèèrè wọ̀nyí: *Bí àwọn ènìyàn tó wá nínú fídíò báṣì wá láyé, ṣe wọn yóò jẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa? Ìlépa wo ní o ròpé wọn yóò jà fitafita fún? Kíni ó jámọ́ fún àwọn ènìyàn yìí láti jẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa? Irú ìwà ìṣesí wo ni wọ́n ní láti lè ṣàwọn àṣeyorí mánigbàgbé yìí?* Èyí lè jẹ́ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àmúrelé tàbí jẹ́ ara ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìtàn nípa àwọn gbajúmọ̀ nínú ìtàn.
- Ní kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe ìwádìí lórí àwọn ẹlòmíràn ní orílè-èdè wọn tí wọ́n rò pé a lè pèní Olùṣọ́-Ìlépa. Ní kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kọ àkọsílẹ̀ ráńpé tí ó ṣàlàyé ìdí tí wọ́n fi rò wípé ó yẹ kí wọ́n jẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa. *Ẹ̀kọ́ wo ní àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè kọ́ lára àwọn ènìyàn yí Ṣé a lè pè wọ́n kí wọ́n wá bá àwọn ọmọ ilé-ìwé sọrọ tàbí kí wọ́n wa gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti gbé ìgbésẹ̀?*
- Ẹnikẹ́ni ló lè ya àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa! Gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti ṣe alábàápín èyí pẹ̀lú àwọn òbí, ẹbí tàbí ọ̀rẹ́ láti polongo à SDGs.
- Ní kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe ìwádìí lórí ayẹyẹ ọlọ́dọdún àwọn Olùṣọ́-Ìlépa lórí (https://www.globalgoals.org/goalkeepers). *Àwọn wo ní àlejò àti olùkópa àtẹ̀yìnwá? Ìgbésẹ̀ ni wọ́n gbé tí àwọn Ìlépa yìí fidi mímúṣẹ? Kíni ìdí tí àwọn ètò ayẹyẹ bàyìí ṣeṣe pàtàkì fún ìmúṣẹ àwọn SDGs?*


SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS · WORLD'S LARGEST LESSON · In partnership with unicef for every child · Supported by AVANTI · With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization · Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION



## Olude Marvelous, Ernest Ogunyemi, àti Amao David – Nàìjíríà

Egbé̩ Aqua jé̩ ẹgbé̩ àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin méta— Olude Marvelous, Ernest Ogunyemi, àti Amao David— tí wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ ìpèsè omi aláìlábàwọ́n tiwa-n-tiwa fún agbègbè wọn nípa lílo eerùpẹ̀ Iṣẹ́ asẹ́ omi aláìlábàwọ́n tiwa-n-tiwa yìí ti wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ó lo àwọn ohun èlò tí ó wà ní àyíká. Èyí túmọ̀ sí wípé iṣẹ́ olówó pọ́kú ni, wọ́n sì ti ń lòó ní ilé-ìwé wọn àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ilé ní agbègbè wọ́n.

**1. Kíni ó jẹ́ ìwúrí/ìmísí fún ẹ láti gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs?**
Ju gbogbo rẹ̀ lọ, àyíká wa ni. Gbígbé ní agbègbè tí ìmọ́tótó jẹ́ èrò ọkàn tàbí àlá lásán, ìlú tí àwọn tí ó ní omi tó mọ́ kò pọ̀ tó àwọn tí ó ń lo ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká. Ní àfikún, kò sí ẹnití o bìkítà, kìí sì ṣe wípé wọn kò fẹ́, ṣùgbọ́n wọn kò ní agbára. Fún ìdí èyí, ohun tí a lè rò ni bí a ṣe lè mú àyípadà wá, àyípadà tí ó túmọ̀ sí wípé àwọn ebí yóò ní omi mímu pẹ̀lú ìgbé àlàáfíà.

**2. Kíni ó jẹ́ ìwúrí ìtèsíwájú ù rẹ?**
Ohun tí ó jẹ́ ìwúrí àkọ́kọ́ fún wa ni ìrànlọ́wọ́ tí atí gbà láti ọwọ́  Beyond School Community Challenge, ètò the Mandela Washington Fellows Alumni ní Nàìjíríà, níbití àwọn adájọ́ àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ṣe onígbọ̀wọ́ iṣẹ́ wa nípa fífún wa ní ẹ̀bùn owó, ṣ'alábàápín ìrírí wọn, tí wọ́n sì tún sọ fún wa bí a ṣe lè mú iṣẹ́ wa gbèrú si. Èyí ni ìbẹ̀rẹ̀ ìwúrí wa. Ṣùgbọ́n, ipa ojojúmọ́ tí iṣẹ́ wa ń kó (bí ó ti lè kéré) láwùjọ àti iye ọ̀dọ́mọdé tí ó ń tẹ̀síwájú bí tiwa ni ó jẹ́ olórí ìwúrí. Iṣẹ́ àkọ́kọ̀ọ wa tí ó jẹ́ pípèsè iná-ọba láti inú afẹ́fẹ́ àwọn ẹ̀gbin fún lílò ní yàrá iṣẹ́ ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ tún ṣe ìwúrí fún wa láti ṣíṣe lórí asẹ́ omi aláìlábàwọ́n tiwa-n-tiwa.

**3. Kín ni ìdí tí o fi lérò pé àwon ọ̀dómodé se pàtàkì fún ìmúsẹ àwon SDGs?**
Ìdáhùn wa ni 'Kin ni ìdí tí kò yẹ kó fí ríbẹ̀?'. Láti ìgbà tí mo ti pàdé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́mọdé jákèjádò Nàìjíríà àti káàkiri àgbáyé ti wọ́n ṣe ìrànwọ́ kí ayé ṣe é gbé, à á ma a wòye irú àrà tí wọ́n lè dá olú àwọn Ìlépa. Àwọn ọ̀dọ́mọdé ní agbára àrà ọtọ̀ tí ó ń fún wọn ní ìpinnu láti sàṣeyọrí ninu ohunkóhun tí wọ́n fi ọkàn wọn sí bíótilẹ̀ jẹ́ wípé ìdojúkọ àti ìkọsẹ̀ lè wà ní ọ̀nà wọn. Ní afikun, àwọn ọ̀dọ́mọdé bílíọ̀nù méjì jẹ́ ohun èlò tó lágbára. Wípé a pọ̀ báyìí túmọ̀ a ṣe pàtàkì nínú àwọn ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní ayé yìí. Àwọn ọ̀dọ̀ tún ṣe pàtàkì nítorí wípé àwọn Ìlépa SDGs yìí jẹ́ ti wọn. Àwọn ọ̀dọ́ ló nílò Ètò Ẹ̀kọ́ tó Múnádóko. Àwọn ọ̀dọ́ ni yóò ṣe ẹlẹ́rìí bí a bá ṣe ṣe ayé yìí.

**4. Ìtumọ̀ wo ni jíjẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa ní sí ọ?**
Jíjẹ́ Olùṣọ́-ìlépa jẹ́ gbígbé ojojúmọ́ ayé ní ọ̀nà tí ó kó ipa dáradára ní agbègbè wa. Ó jẹ́ ìdùnnú tí a ní wípé ẹnìkan níbìkan nínú àbò. Ó túmọ̀ sí wípé a kò pàdánù àwọn ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin sí orísirísi àrùn inú omi ti ó  ti ṣe ikú pa ọjọ́ iwájú ilẹ̀ Áfríkà àti àwọn ibòmíràn l'ágbàáyé.



SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS WORLD'S LARGEST LESSON In partnership with unicef for every child Supported by AVANTI With thanks to UNESCO Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION




## Comfort Ijaola, Victor Aromose àti Alfred, Adeyemi láti Nàìjíríà

Comfort, Victor àti Alfred kẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ìpele kọkànlá àti ìkẹjọ ní ilé-ìwé tí ó gbajúmọ̀ ní gúúsù Nàìjíríà tí wọ́n sì ń gba ọ̀nà àrà kojú ìwà ìbàjẹ́ ìfipá bánilòpọ̀ ni orílè-èdè Nàìjíríà. Bí ìwà ìbàjẹ́ yìí se ń gbèrú si ní agbègbè wọn ni ó mú kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí gbé ìgbésẹ tí ó dúró ṣinṣin ní ilé ẹ̀kọ́ àgbà. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ṣíṣe papọ̀ láti dá Just Nig Project sílẹ̀. Iṣẹ́ yìí ni àkọ́kọ́ irú rẹ̀ tí ó fi jẹ́kí Nàìjíríà kópa nínú Global Diamond Challenge ni ìpele tí ó kẹ́yìn ní ọdún 2019.

**1. Kíni ó jẹ́ ìwúrí/ìmísí fún ẹ láti gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs?**

Gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ a ri wípé àwọn ọ̀dọ́bìnrin ní Nàìjíríà ní àwọn ìdojúkọ tí ó ọ pàápàá jùlọ ìfipá bánilòpọ̀. A ri wípé ìṣòro yìí ń gbèrú si lójoojúmọ́ gẹ́gẹ́ bí èèkádẹ̀rí. Ìrírí ti ara wa àti ẹ̀ri àwọn ènìyàn gbé wa ninu láti gbé ìgbésẹ fún Ìlépa Karún— Ìbádg a Láàrin Ọkùnrin àti Obìnrin.

**2. Kíni ó jẹ́ ìwúrí ìtèsíwájú ù rẹ?**

Ìmọ̀ ẹ̀rọ ló ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wa lórí ìṣàṣeyọrí Ìlépa wa. Ó mú wa tẹ̀síwájú láti ìbẹ̀rẹ̀ wa. Ìtara tí a ní sí èròngbà/ìlépa yìí tún mú wa tẹ̀síwájú. Lílo ẹ̀rọ ayélujára jẹ́kí a ní anfààní láti kó ipa tó péye láyé àwọn ènìyàn káàkiri àgbáyé. Àpẹẹrẹ èyí ni ìtàkùn àgbáyé tí a dá sílẹ, tí ó ń mú Ìlépa yìí ṣẹ. Àwọn èsì dáradára tí à ń rí gbà tún fún wa ní ìwúrí láti tèsíwájú.

**3. Kín ni ìdí tí o fi lérò pé àwon ọ̀dómodé se pàtàkì fún ìmúsẹ àwon SDGs??**

Àwọn ọ̀dọ́ pọ̀ jántìrẹrẹ ní àgbáyé ní àsìkò yìí. Èyí fi yé wa wípé bí àwọn ọ̀dọ́ bá ọ ní iṣẹ́ ìtara báyìí, àwùjọ wa yóò dàgbà sókè. Ní òtítọ́, ṣíṣe àmúṣẹ irú àwọn Ìlépa bayii yẹ kí ó rú àwọn ọ̀dọ́ sókè nítorí wípé ìtara Jésù ìṣesí àwọn ọ̀dọ́.

**4. Ìtumọ̀ wo ni jíjẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa ní sí ọ?**

Jíjẹ́ Olùṣọ́-ìlépa máa ń jẹ́ kí a mọ si nípa àwùjọ wa. Ó ń jẹ́ kí a ran agbègbè wa lọ́wọ́, a sì tún ní anfààní láti ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn tí afiwàjọ láti lè mú àwọn ìlépa wọ̀nyí ṣẹ lẹ́kùnrẹ́rẹ́. Àpẹẹrẹ èyí ni ìbáṣepọ̀ wa ní Just Nig pẹ̀lú Saviours tí wọ́n jẹ́ bíi Olùdámọ̀ràn, Ajàjàgbara, Olùwòsàn àti Oníròyìn.


SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION



## Memory Banda láti Màláwì

Memory jẹ́ agbẹnusọ takuntakun tí ó ń dẹ́kun ìfọmọdé lọ́kọ. Memory kọ̀ láti lọ́kọ lọ́mọde. Kàkà bẹ́ẹ̀, ó bá àwọn olóyè abúlé rẹ̀ ṣiṣẹ́ láti ṣ'òfin tó ń dáàbòbò àwọn ọmọdébìrin lọ́wọ́ fífi lọ́kọ. Iṣẹ́ rẹ̀ ti jẹ́ k'àwọn aláṣẹ sún ọjọ́ ori fún ìfilọ́kọ sókè sí odún méjìdínlógún. Láti kà si nípa iṣẹ́ Memory tẹ [here](here).

**1. Kíni ó jẹ́ ìwúrí/ìmísí fún ẹ láti gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs?**

Dídàgbà ní ọ̀kan nínú àwọn ìlú t'ótòṣì jùlọ kìí ṣe ohun to rọrùn rárá, pàápàá júlọ gẹ́gẹ́ bi ọmọbìrin. A dàgbà láìní agbára láti yàn; àwọn àǹfàní ìgbé ayé kò sìsí níbẹ̀. Ó bani nínú jẹ́ wípé àwọn ènìyàn dàgbà láìmọ̀ wípé àwọn ní ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn tí ó ṣe é dáàdòbò. Ohun tí ó dinu jú ni kí n rí àwọn ẹlẹgbẹ́ míi l'óbìrin kí wọ́n má le sọ̀rọ̀ tí abá gbojú ẹ̀tọ́ wọnmọ́ lẹ̀ tàbí tí wọ́n bá ń ní ìdojúkọ. Ẹ̀kọ́ jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀tọ́ ọmọ-ènìyàn tí ó ṣe pàtàkì, sùgbọ́n ọ̀pọ̀ àwọn ọmọbìrin ni kò ní èyí. Nígbàtí morí bí wọ́n ti ń f'ọmọdé lọ́kọ nínú ẹbí mí, láàárín àwọn ọ̀rẹ́ nì ati nínú àwùjọ mi; mo pinnu láti jà fún wọn. Ìgbéyàwó ọmọdé jẹ́ ọ̀kan lára àwọn àṣà tó panilára tí ó sì tún ní ipa lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọbìnrin t'óyẹ kó wúlò fún ìlú àwọn. Mo rò wípé ó tó àkókò kí àwọn ọmọbìnrin ní àǹfàní kannaa lati gbé ilé-ìwé kí wọ́n sì kópa tóyẹ ní àwùjọ, nínú òṣèlú ati ọrọ̀ ajé.

**2. Kíni ó jẹ́ ìwúrí ìtèsíwájú ù rẹ?**

Ohun tí ó ń gbà mí níyànjú ni àwọn ìtèsíwájú tí à ń ní. Àwọn ọmọbìnrin ti ń dìde borí ìdojúkọ wọn, wọ́n sì tún jára wọn gbà lọ́wọ́àṣà àdáyébá. Àwọn ọmọbìnrin ń jà fún ara wọn, wọ́n sì tún ń mú àyípadà bá àwọn agbègbè wọn, wọ́n ń di olórí, olùṣàyípadà wọ́n sì tún jà fún àwọn ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn. Ẹ̀yí fi hán wípé ìdógba láàrín okùnrin àti obìnrin (èròngbà karùn-ún/Goal5) jẹ́ ìlépa tí yóò wá sí ìmúsẹ.

**3. Kín ni ìdí tí o fi lérò pé àwon ọ̀dómodé se pàtàkì fún ìmúsẹ àwon SDGs?**

Àwon òdómodé ni o n ni ìmọ̀lára awon àkùdé ìlépa kọ̀ọ̀kan, nípa bẹ́ẹ̀, ó se pàtàkì kí àwon ọ̀dómodé kópa nínú gbogbo isẹ́ tó nípa nínú ìgbésí ayé won ní ibi gbogbo lágbàáyé. Láì sí àwon òdómodé, àwon ìlépa yìí kòlè di mímúse. Èròngbà tó borí gbogbo àwon SDGs yìí ni kí à mà fi/yọ enikeni sílẹ̀. Àwon ọ̀dọ́mọ́dé ní láti kópa nínú gbogbo nǹkan ka ba lè ní ìpìlẹ̀ tó dúró ṣinṣin fún àwon ìran tó ń bọ̀ ní ojọ́ iwájú.

**4. Ìtumọ̀ wo ni jíjẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa ní sí ọ?**

Láti lè jẹ́ Olùṣọ̀-Ìlépa, o gbọ́dọ̀ lè tọ́ka sí ìṣòro kan lágbègbè, mọ ohun tó yẹ kí o ṣe, gbé ìgbésẹ̀ nípa jíjẹ́ asájú, bẹ̀rẹ̀ sí ronú lọ́nà ọ̀tọ̀ ki o sì gbàgbọ̀ pé àyípadà yóò ṣẹlẹ̀. Kò sì sí agbára àrà ọ̀tọ̀ láti di Olùṣọ́-Ìlépa, gbogbo wa la lè di Olùṣọ̀-Ìlépa nípa yíyan ọ̀kan lára àwọn Ìlépa Ìdàgbàsókè To Dúró Ṣinṣin, kí o sì máa làkàkà fún ìtèsíwájú. Àyípadà máa ń wáyé tí ìtara, ìpinnu àti ìgbésẹ̀ bá wà.


SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION



## Ndubuisi Uchea & Hayel Wartemberg láti UK

Ndu àti Hayel jẹ́ olùdásílẹ̀ Word on the Curb – ẹgbẹ́ tí ó wà láti ní òye, ìtàn, ìdánimọ̀ àti àṣà. Ndu àti Hayel fẹ́ ṣe ìwádìí lórí èrò òdì àti ìsọlẹ́nu tí ó rọ̀ mọ́ oríṣiríṣi ẹ̀yà jákèjádò àgbáyé, ní lílo Word On The Curb gẹ́gẹ́ bí ohun èlò láti ṣe èyí. Word On The Curb just ohun èlò tí àwọn ènìyàn gbà ṣe alábàápín ìtàn wọn àti ka ìtàn ẹlòmíràn. Wọ́n tún máa ń ran àwọn okòwò le nípa títa won lólobó lórí àṣà àwọn ọ̀dọ́. Wọ́n sì tún máa ń pèsè àwọn ànfàní fún àwọn ọ̀dọ́mọdé láti kọ kí wọ́n tún ni ìbáṣepọ̀ láàárín àwọn tó jáfáfá.

**1. Kí ni ó jẹ́ ìwúrí/ìmísí fún ọ láti gbé ìgbésẹ̀ fún àwọn SDGs?**

Àwa méjèèjì dàgbà ní ìlú, Londonu, tí ó oríṣiríṣi àṣà àti ẹ̀yà. Alọ sí ilé-ìwé ní Manchester, ó di mímọ̀ fún wa wípé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a dàgbà ní ìlú yìí, a ní òye kúkurú lórí ìrírí àgbáyé àti pàápàá jùlọ àwọn oríṣiríṣi àṣà àti ìdánimọ̀ tí ó wà nínú rẹ̀. A lérò wípé ànfàní wà fún wa láti ßí ojú ọpọn fún ìwádìí itan oríṣiríṣi awọn ènìyàn láàárín ọgbà ilé-ìwé. Bí a bá kàwé jáde, a fẹ́ gbé èyí kọjá ilé-ẹ̀kọ́ gíga àti Manchester. Gẹ́gẹ́bí ẹnití ó ti ní ìrírí àìfinipeni, a mọ́ ipa búburú tí ó wà nínú àìní òye àwọn àṣà míràn. Jù bẹ́ẹ̀ lọ, a fẹ́ dẹ́kun ìwà yìí.

**2. Kíni ó jẹ́ ìwúrí ìtèsíwájú ù rẹ?**

Lílo fídíò fún wa ní ànfàní láti ní ipa tí ó pọ̀ lórí àwọn ènìyàn l'ágbàáyé. A ti ṣe oríṣiríṣi iṣẹ́ tí àwọn ènìyàn ti wò káàkiri orígun àgbáyé. Àpẹẹrẹ èyí ní fídíò ìlúmọọ̀kà ti a pè àkọ́lé rẹ̀ ní "Ohun Ti Wọn Kò Kọ́ Mi Ní Ilé-ìwé". Fídíò náà ṣe àfihàn bi ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ kọ́lẹ́ẹ̀jì kan ṣe kojú olùkọ́ rẹ̀ lórí kíkọ́ ìtàn àwọn ènìyàn dúdú ní àwọn ilé-ìwé. Ogójì mílíọ̀nù eniyan ni ó ti wo fídíò yìí ní oríṣiríṣi àwọn sóṣíà midià (social media). A sì tún n gba àwọn ìwé lati Lèsóthò dé Louisiana tó ń sọ nípa ipa rere tí fídíò náà ti kó ní orí olúkúlukú, ilé-ìwé, ẹbí àti àwùjọ. A ní àwọn ẹbí lati Nàìjíríà and Ghana tí wọ́n fi fídíò yìí ránṣẹ́ sí wa lórí WhatsApp láìmọ̀ wípé àwa la ṣ'èdá rẹ̀! Irú àwọn èsì báyìí ni o gbà wá níyànjú.

**3. Kín Ni Ìdí Tí o Fi Lérò Pé Àwon Ọ̀dómodé Se Pàtàkì Fún Ìmúsẹ Àwon SDGs?**

A ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀dọ́mọdé ní àgbáyé ju àtẹ̀yìnwá lọ (Ní àfojúdá, á á tó bílíọ̀nù méjì tí ó jẹ́ ọmọ odún mẹ́wàá sí mẹ́rìnlélógún). Èyí túmọ̀ sí wípé lílo wọ́n kì í ṣe pàtàkì nìkan ṣùgbọ́n ohun ìṣájú jùlọ láti lè s'àmúye Ilepa. Àwa ọ̀dọ́ la kọ́kọ́ lo WhatsApp ati Facebook kí àwọn òbíi wa tó bẹ̀rẹ̀ sí ní lò ó. Àwa lasì kọ́ wọn. Nípa bẹ́ẹ̀, lílo àwọn ọ́dọ̀ jẹ́ ohun tó ṣe pàtàkì.

**4. Ìtumọ̀ wo ni jíjẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa ní sí ọ?**

Jíjẹ́ Olùṣọ́-ìlépa jẹ́ ìrántí ojojúmọ́ pé a ní ojúṣe láti ran agbègbè wa lọ́wọ́ lati dára sí fún ìgbé and wíwà papọ̀ pẹ̀lú ará wa. Ó jẹ́ àwùjọ àwọn tí ó fiwà kọni. Àwọn Olùṣọ́-ìlépa yòókù gbà láti ṣiṣẹ́ papọ̀ kí ọrùn má ba wọ eniyan nítorí àwọn èròngbà ti àwọn SDGs gbé kalẹ̀. Ó ṣe é ṣe. A ó sì múuṣẹ.



SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION






SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS | WORLD'S LARGEST LESSON | In partnership with unicef for every child | Supported by AVANTI | With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization | Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

## **Appendix 6:** Àkójọ àwọn Ọ̀rọ̀ fún Áàpù Olùṣọ́-Ìlépa (the Goalkeeper App)

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ pẹ̀lú **àwọ̀ ewé** jẹ́ àwọn ọgbọ́n ìṣe tí a sàfihàn rẹ̀ nípa kíkọ́ nípa àwọn SDGs . Àwọn ọ̀rọ̀ tí ó wà ní **búlùù** àwọn ọ̀rọ̀ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè mẹ́nu bà lórí áàpù Olùṣọ-Ìlépa (the Goalkeeper app). Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò mú mẹ́ta ninu àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí fún àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa wọn.

1. Nígboyà
2. Láàbójútó
3. Alátunúdá
4. Lófìntótó
5. Nípinnu
6. Lákitiyan
7. Dunnú/Láyọ̀
8. Ṣèwúlò
9. Lérò
10. Dára
11. Lóòótó
12. Gbàmóra
13. Lágbára
14. Láròjinlẹ̀
15. Ìfọkàntán
16. Ajàjàgbara
17. Arìnrìn ajo fún ìmọ̀
18. Òṣèré
19. Eré-ìje
20. Arákùnrin
21. Olùpolongo
22. Olùṣàyípadà
23. Aṣètò
24. Aláfojúsò
25. Òǹtajà
26. Agbátẹrù àyíká
27. Ọ̀rẹ́
28. Olùdásílẹ̀
29. Olórí
30. Aṣèṣirò
31. Olórin
32. Onírètí
33. Onímọ̀-ìjìnlẹ̀
34. Aràbìrin
35. Òǹsọ̀tàn
36. Akẹ́kọ̀ọ́
37. Aríran



SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS · WORLD'S LARGEST LESSON · In partnership with unicef for every child · Supported by AVANTI · With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization · Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

## Appendix 7: Itọ́sọ́nà lórí Bí a Ṣe ń Lo Áàpù Olùṣọ-Ìlépa (Goalkeeper App)

1. Ya fọ́tò ara rẹ tàbí kí o ní kí enìkan ó yà é. Ríi dájú pé o lè rí ojú ara rẹ àti wípé ò ń rẹ́rìn-ín músẹ́. Ó gbọ́dọ̀ jẹ́ fọ́tò tí ojú rẹ hàn gedegbe nínú rẹ̀. kò nílò kí ara rẹ yòókù hàn nínú rẹ̀. Tọ́jú èyí sí orí ẹ̀rọ kọ̀mpútà rẹ..

2. Lọ sí orí Áàpù olùṣọ-ìlépa: http://wllgoalkeeperme.globalgoals.org/

3. Tẹ ààmì kámẹ́rà láti gbé fọ́tò rẹ sí orí rẹ̀.

4. Lo àwọn ààmì tí ó wà ní apá ọ̀tún lókè àpótí àwòrán kọ̀ọ̀kan láti ṣe àwòrán rẹ bí o ṣe fẹ́. Àmì "A" ni ibi tí o ó ti mú àwọn ọ̀rọ̀ rẹ, búrọ́sì ìkunọ̀dà yóò yí àwọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ rẹ padà. Inú Àwòrán ribiti tí ó kún láábọ̀ lo ti lè mú àwọ̀ tó wùn ọ fún àwọn ìpínrọ̀ rẹ.

5. Kí o tó fi fọ́to rẹ pamó sí orí áàpù, ríi dájú wípé o ka àwọn òfin àti ipò tí o wà fún áàpù olùṣó ìlépa ní tí tẹ  Terms and Conditions of the Goalkeeper app.

6. Ònà méjì ni o wà tí o le gbà fi àwòrán rẹ pamọ́: nípa títẹ bọ́tìnnì búlù tí ó dúró fún fipamọ, yóò gbà á sórí kọ̀mpútà rẹ lọ́gán. Tàbí kí o tẹ bọ́tìnì fipamọ́ sí gálẹ́rì. Yóò fi pamó, yóò sì tún gba àwòrán olùṣọ-ìlépa rẹ sílẹ̀ lórí èrọ kọ̀mpútà rẹ àti lórí àwọn àkójọpọ̀ fọ́tò fún gbogbogbòò.

7. Jọ̀wọ́ ṣalábàápín àwòrán olùṣọ-ìlépa lori twitter/Instagram
   Twitter: @WorldsLessonNG Facebook: @WorldsLessonNG
   Instagram: @WorldsLessonNG  email: worldslessonnigeria@outlook.com



SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION

# Àwòrán Olùṣọ́-Ìlépa Mi

WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef

**Ìtọ́nisọ́nà**

- Lo dígí tàbí fọ́tò láti yà tàbí kun àwòrán yìí.
- Yan ọ̀rọ̀ mẹ́ta tó ṣàpèjúwe ìdí í o fí jẹ́ Olùṣọ́-Ìlépa
- Ṣalábàápín àwòrán rẹ pẹ̀lú ẹlòmíràn!






SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS
WORLD'S LARGEST LESSON
In partnership with unicef for every child
Supported by AVANTI
With thanks to UNESCO United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization
Endorsed by FEDERAL MINISTRY OF EDUCATION